E ma ka Irohin Imo-le Ni Igba Gbogbo

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

READY FOR SALE
Iwe Arofo ti -:
ANỌYIN LOHUN-BI-ỌMOGE- IMARO
APA KETA
LATI ỌWỌ
G. A. SOWUNMI
Price 2/-
Modupe Press
16, Bamgbose Street,
Postage Extra

VOL. I No. 50 WEDNESDAY JUNE 11, — JUNE 17 1958 KỌBỌ KAN

# Won da adorun enia pada ninu awon ti nlo si "Mecca" pada wale

Adorun ninu awon to nlo si Adji ti nwon si de Mecca ni won da pada nitori ko si ona ti nwon le fi gba jeun, loro kan, ko si owo lowo won mo, were ni Ijoba si ti da won pada si Kano,

Awọn marundin-ladọta miran ni Ijọba tun da pada a ko awọn wonyi sinu mọto lọ si Ile-Iwosan fege, a tọju wọn si ihin nitori ìko tun si ibomiran ti a tun le ko wọn si mọ.

Awọn ẹlomiran gba ihin lọ si ile wọn, sugbọn awọn ẹlomiran si nsun nihin, awọn ẹlomiran si nsun ni ile awọn ti nsisẹ ni Ile-Iwosan.

Awọn ti yio pada lọ si ile wọn ni:—Alhadji Ibrahim Hadejia, Alhadji Muhammed Hadejia, Alhadji Musa Kabawa Ringim, Alhadji Limun Yerwa ati aya rẹ Amina, Alhadji Ibrahim ati Aya rẹ, Alhadji Lawani Ojulari ati Alhaji Sanni Ajisafẹ.

Ibrahim Hadejia ẹni ọdun ogoji sọ wipe ọpọlọpọ ninu awọn ti wọn lọ si Mecca ni wọn ko de ọhun tan. O si ni ogunlọgọ ni wọn tan sọna.

O si fi han wipe ai ni owo lọwọ ni o jẹ ki ẹlomiran tan sọna, o ni oun jẹ ikan ninu awon wọnyi sugbọn o ni oun ya ni ilu Gadari nitosi Katunu, nihin ni oun gbe nse iṣẹ agbẹ ti o un si fi ri owo lati tun ba irin ajo oun lọ, o ni oun wa nihin fun ọdun mẹta.

Alhadji Muhammadu Hadeija wipe ọpọlọpọ ni wọn tan si ilu Sudan, ṣugbọn wọn ko ni pada nitori wọn nba iṣẹ owo lọ gidigidi.

A bi awọn ẹlomiran si hin, ṣugbọn nitori baba ati iya won ti ku, won ko mo ibi ti won ti wa ni Ilu Nigeria.

Ṣugbon awon ẹlomiran tan sona nitori ai to owo.

Lawani Ojulari ẹni adọta ọdun fihan wipe oun ba ọkọ ofurufu kuro nihin ni ọdun ti o kọja lati lọ si Mecca, ṣugbọn nigbati oun ma fi pari gbogbo nkan ti oun lọ ṣe ni Mecca ni aisan kọlu oun to bẹ ti ko si owo lati pada mọ.

Ọgbẹni Lawani Ojulari yi wa lati Oke-Ode, Lawani yi tun fi nhan wipe ọpọlọpọ ninu awọn ti a da pada wọnyi ni wọn wa lati ilu Bornu, Nupe ati Banufe ni agbegbe Benue. Oluwa yio sọ gbogbo wọn o, ki nwọn ma ri aisan ti yio le ju wọn lọ Amin.

## Owo oko Reluwe yio sun soke die si

AWỌN alaṣẹ ibiṣẹ ọkọ ilẹ ti a npe ni Reluwe, fi ye wa wipe awọn ko le ṣe ki nwọn maṣe gbe iye owo ọkọ ilẹ ga diẹ nitoripe owo ti nwọn nta awọn ohun elo ti nwọn fi nṣiṣẹ ti o si nṣe iṣẹ yi, owo diẹ ko ka wọn lenu mọ. Larin ọdun mẹta ti o ti kọja si akoko yi, nṣe ni inawo tunbọ ngori inawo fun wọn.

Owo 1st Class ti nwọn ti nsan ni kọbo mẹrin 4d tẹle ri, owo rẹ yio di kọbọ marun 5d nisisiyi fun ibusọ kan, 2nd Class ti nwọn ti ngba kọbọ meji 2d fun ibusọ kan yio di kọbọ meji abọ, ọkọ ero ti awọn mẹkunnu 3rd Class ti nwọn ti nwọ ni ọnini mẹta yio di kọbọ kan fun ibusọ kan.

Iwọnyi ni iye owo ọkọ reluwe da.

Lati Eko si Ibadan ti a ti nwọ ni ṣile meje abọ 7/6d yio di ṣile mẹwa 10/-, lati Eko si Jebba ti a ti nwọ ṣile mọkandinlogun 19/- yio di ṣile mẹdogbọn ati toro, lati Eko si Minna ti a nwọ ni ṣile mọkandinlọgbọn 29/- yio di ṣile mejidinlogoji ati sisi 38/6d, lati Eko si Kaduna ti a ti nwọ ni ṣile marundinlogoji 34/- yio di ṣile merindinladọta ati nain 46/9d lati Eko si Kano ti a ti nwọ ni ṣile mẹrinlelogoji 44/- yio di ṣile ṣile mejidinlọgọta ati kọbọ merin 58/4d, lati Eko si Enugu ti a ti nwọ ni ṣile mọkanlelọgọta 61/- yio di ṣile mọkanlelọgọrin ati kọbọ meje 81/7d, lati Eko si Port-Harcourt ti a ti nwọ ni ṣile mọkanleladọrin 71/- yio di ṣile mẹrinleladọrun ati kọbọ meji 94/2d.

## Dr. Azikiwe ba Oniwe Irohin Soro.

Kaduna

Dr. Azikiwe lo nba awọn oniwe Irohin sọrọ nilu yi o ni on ko ji yan bi awọn enia ba sọ wipe, nṣe ni on wa ba Sadauna mulẹ. Ole jẹ wipe eyi ti nwọn wi ni jẹ otitọ tabi ko se otitọ ṣugbọn niti on, ẹnikan ko ni gbọ idi rẹ lẹnu mi.

Nwọn bere lọwọ rẹ wipe



Dr. Nnamdi Azikiwe.

njẹ bi o ba jẹ wipe lotitọ ni Azikiwe wa ba ẹgbẹ N.P.C. mulẹ, nibo ni yio fi ti ẹgbẹ N.E.P.U. si? o dahun pe, on ko ni ọrọ kan lati sọ.

Nwọn tun bere pe, o ha tọ ki ọlọpa Hausa wa ni ilẹ Hausa, ki Yoruba wa nilẹ Yoruba ki Ibo si wa nilu rẹ bi? Azikiwe dahun pe, ọrọ yẹn di ilu Oyinbo, nigbati nwọn ba lọ ṣe igbimọ bi a ba si de ọhun tan emi ko ni kọkọ danu le ọrọ na, afi bi Sadauna ba danu le.

O sọ fun awọn Oniwe Irohin pe Ijọba Ila orun ti dawọ le ilọsiwaju kan ni iha Ila-orun, ṣugbọn nṣe na ti duro tiiri awọn yio fi ri owo fun. Nkan ti Ijọba nṣe nisisiyi ni pe, ki agbegbe Ila orun leni ilọsiwaju.

# IMOLE

ESIN ORO WA:- IMOLE DE OKUNKUN PARADA

*EDITORIAL WORKS & OFFICE*

**16, Bamgbose Street, Lagos**

**Telephone:- 21985**

*London Office:-*

*Sunday Ayorinde:- 5, Hemming Street London E. 1.*

UNITED KINGDOM REPRESENTATIVE
PUBLISHING DISTRIBUTING CO. LTD. MITRE HOUSE
177, Regent Street, London W. 1.

FUN OWO "IROHIN IMOLE" ODUN KAN
EKO— Şile Mẹrin ati Kọbọ Mẹrin (4/4d)
Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun, Şile Mẹfa ati Kọbọ Mẹfa (6/6d)


## Lowo Iku Ojiji Oluwa Rere Gbawa

GBOGBO ẹnyin ọbi awọn ti ọkọ danu sinu omi ni Eko tabi ni ilu miran. A ki nyin, ẹ ku ajalu ,ẹ ku ara fẹ ara ku. Ẹnyin ara Eko a ki nyin ẹ ku ara fẹra-ku, Oluwa ko ni jẹki a ri irufẹ eyi mọ. Ẹnyin enia ti ẹ nwọkọ YASAIDI, a kesi nyin wipe enia ki iku ko tun jẹbi iku, nitoripe ẹmi wa yi ko pe meji bikoşe ẹyọ-kan, Oluwa ko ni şe wa loku omi, şugbọn ki awa na maşe şe ara wa ni oku omi nitoripe ọkan ninu awọn ti Ọlọrun yọ ninu ewu ọkọ na nfi ye wa nigbati a nşe ibere lọwọ rẹ ohun ti o mu u wọ ọkọ YASAIDI o si dahun wipe ki o ba le ya oun ni. Ha! enyin ara ẹ maşe jẹki a kanju lọ sọrun are mabọ, awọn toku ti lọ, şugbọn eyiti a nsọ yi fun awa toku lori ilẹ aiye ni ẹnikẹni to ba fẹ kio gbọ, ẹyi ti o ba si fẹ o ku sọwọ rẹ.

Ẹnikẹni toba fẹ lọ sibi ti o mu ikanju wa, o dara fun oluwarẹ ki o tete jade nile ki akoko to to, biko si şe bẹ, ẹ le lọ wọ ọkọ Katilini eyi ti oyinbo şe ti o si dani loju wipe ti ko ba si amuwa Oluwa tabi ti eşu, jamba kan ko le şẹlẹ rara ninu rẹ, tabi bi bẹkọ ki ẹ şe agbara lati şe inawo mọto ayọkẹlẹ (Takisi) ti yio gbe nyin de ojule ibiti ẹ fẹ lọ ni işẹju akan, laiko şe ọkan ninu awọn imọran wọnyi, ki oluwarẹ joko ni ile rẹ.

Ẹnyin ti ẹ fi igbadi jamba ọkọ ti o danu, Oluwa yio pa aşiṣe nyin rẹ, yio gbe nyin si afẹfẹ rere, Oluwa yio tu awọn obi, ọmọ, ati ojulumọ ti ẹ fi silẹ ninu. O digbere, o di arinnako, o di oju ala, ohun ti nwọn ba njẹ lajule ọrun ni ki ẹ ma ba wọn jẹ. O DIGBERE

## AWON IWE KOSEMANI TI O WA NILE FUN TITA NISISIY


| | |
|---|---|
| Afọşẹ Işẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan | 2/6d |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan pẹlu Itumọ Ala | 20/- |
| Itan Aladun lede Yoruba | 3/- |
| Ajiran Ilu Oku | 3/- |
| Waka Bistriyu Apalara | 1/- |
| Itumọ Ala ati Itumọ Ami ′ra | 3/- |
| Iwe Owe Yoruba | 3/- |
| Psalm Işẹgun Ajẹ ati Aiye pẹlu Turari | 17/6d |
| Turari Itaja, Eyọnu Ajẹ ati Adura | 10/6d |

Fi owo ọja rẹ ati 1/- ranşẹ si :-
Fi owo ati Stamp 1/- ranşẹ fun gbigbe ọja rẹ pada
J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Mẹtta
Tabi
8, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin,

AWỌN IWE TI A ŞEŞẸ FẸ TẸ JADE

Igbo Esubeleke (kikun) 4/6d, Irin Ajo Ajanpako (kikun). 4/6d Ayunọranbọ ati Panpalaşo 4/6d, Ajiran Ilu Oku (kikun) 4/6, Şebotimọ Ọrẹ mi 3/-, Mafarọ Şere 3/-, Igba ko lọ bi Orere 3/-

Akiyesi :- Ẹ o ma gbọ nigbati o ba jade


# IDAHUN SI IBERE

## PETE-PETE TANA NI POPA

EMI Owuyẹ-aşoro-sọ-bi-ọrẹ, baba alawiye ki iwọ Ọgbẹni Pẹtẹ-pẹtẹ-tana-ni-pọpa pupọ, o ku ọgbọn, o ku oye, o si ku ilakaiye pẹlu. Ọrọ Ọlọrun ko fa ija, abere ọrọ ni o nşe, mo si şe tan lati fun ọ ni esi ibere rẹ.

Ọjọ pẹ diẹ ti mo ti ngburo rẹ, inu mi si dun lati şe alabapade rẹ loni.

Iwọ ọrẹ mi, takute ti o dẹ fun aparo, Agilinti lo mu. Gẹgẹbi igbagbọ rẹ ati ti gbogbo enia, Ẹmi ni Ọlọrun, awọn ti o si ni igbagbọ ninu Ẹmi Mimọ a ma pe ara wọn ni Onigbagbọ, Ẹmi mimọ yi ti işe Ọlọrun tobi pupọ, bi awa ko ti le ri ni i, şugbọn on ri wa, o mọ ohun gbogbo, o si le şe ohun gbogbo, lati ọwọ Ẹmi Mimọ yi ni Maria ẹniti nşe Wundia ti loyun Jesu. Eyi yi si fun wa ni igbagbọ pe Ẹmi Mimọ ti işe Ọlọrun ni baba Jesu, Jesu si ti idi eyi di ọmọ Ọlọrun.

Pẹtẹ-pẹtẹ-tana-ni-pọpa, oye rẹ ku diẹ ki o pe nipa iye Ọlọrun ti o wa. Ọlọrun kan ni mbẹ. Ninu Ọlọrun kan şoşo yi ni baba, ọmọ, ati ẹmi wa, apapọ wọn ni a npe ni Ọlọrun. Jesu ti işe ọmọ kanşoşo sọ nipa ara rẹ bayi pe, 'Emi nbẹ ninu baba, baba si nbẹ ninu mi'. Ni iwọn igbati Ẹmi Mimọ ti işe Ọlọrun ni o so baba ati ọmọ pọ, a ko le ya wọn sọtọ, eyi si fi han kedere pe Ọlọrun kan şoşo ni o wa, ki o ba le ye ọ si, iwọ Ọgbẹni pẹtẹ-pẹtẹ-tana-ni-pọpa, o gba ninu ibere rẹ pe Ẹmi Mimọ ni Ọlọrun, itunmọ Ọlọrun baba, Ọlọrun ọmọ ati Ọlọrun Ẹmi mimọ ni eyi. Ẹmi baba, Ẹmi ọmọ, Ẹmi mimọ tikalara rẹ, awọn mẹtẹta si jẹ ọkanşoşo.

Idi rẹ ti awọn ti nwọn gba Jesu gbọ, ti nwọn a si ma pe ara wọn ni onigbagbọ şe npe ara wọn ni ọmọ Ọlọrun ni wipe, nwọn gbagbọ pe Ẹmi mimọ ti işe Ọlọrun wa ninu awọn, ati gẹgẹbi igbagbọ wọn ninu Jesu ti o fi irẹlẹ pe ara rẹ ni ọmọ Ọlọrun, awọn

(Wo oju ewe kẹta)

THE COMRADES By Scorpio No. 32



"Whom did you learn to hate today, dear?"

